# Fífún Ọmọ Lọ́yàn Láìfi Omi Làá



## Àlàyé nípa rẹ̀:

- Ìlànà fífún ọmọ lọ́yàn láì fi omi làá jẹ́ Ìlànà ìfètòsọ́mọ bíbí tí alẹ̀ lò fún ìgbà díẹ̀.
- Ó lè sisẹ́ dáada fún obìnrin tí óbá tèlé Ìlànà mẹ́ta yìí:
  - Ọmọ owọ́ rẹ̀ kò tíìpé oṣù méfà
  - Ó ń fún ọmọ lọ́yàn (ní gbogbo ìgbà t'ọ́mọ bá fẹ́, tọ̀sán-tòru) láìfi ọmi làá tabi oúnjẹ míràn fún ìkókó
  - Ǹkan oṣù rẹ kò tí ì dé láti ìgbà tó o ti bí ọmọ náà

## Báwo ni Fífún ọmọ Lọ́yàn Láìfi Omi làá ṣe lè sisẹ́ sí?

- **98% ni ólè sisẹ́ fún:** Bí obìnrin ọ̀gọ́rùń bà lò Ìlànà yí, bí méjì nínú wọn ni yíò lóyún ní àárín oṣù méfà lẹ́yìn tí ó bímọ náà

## Àlèèbú to le jẹyọ:

- Kò sí

## Báwo ni óṣe ń sisẹ́?

- Ìlànà yí ń dènà fún obìnrin láti yé ẹyin tí ó pòn. Èyí túmọ̀ sí wípé obìnrin kò ní yé eyin ní oṣoòṣù. Bí eyin kò bá si pàdé àtò, oyún kò lè dè.

## Ànfààní rè:

- Á le è ló ní kété tí a bá bí ọmọ tán
- Kò dí ìdálòpò tọkọtaya lọ́wọ
- Kò nílò ìnáwó míràn tàbí ohun èlò kankan
- Kì jé kí ǹkan oṣù àwọn obìnrin míràn kí ó wá
- Fífún ọmọ lọ́yàn yíó jẹ́ kí ìkókó ri oúnjẹ tí ódara jùlo jẹ

## Tani kò lè lò ó:

- Obìnrin tí ọmọ rẹ ti ju oṣù mẹ́fa lọ
- Obìnrin tí ǹkan oṣù rẹ tí padà dé
- Eni tí óń fi oúnjẹ míràn fún ọmọ yàtọ̀ fún ọyàn tàbí tí a tí fi omi lá oúnjẹ ọmọ

## Tani ó lè lò ó

## Obìnrin tí ó:

- Ṣẹ̀ṣẹ̀ bímọ tí kò tí pé oṣù mẹ́fà
- Ǹkan oṣù rẹ kò ìtí padà dé
- Ńfún ọmọ lọ́yàn ní ìgbà gbogbo (tọ̀sán-tòru)

**Akiyesi:**
Bí obìnrin bá ní ìsòro láti fún ọmọ lọ́yàn, bá akọ́sẹ́mọsẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí sọ̀rọ̀

